# ÒFIN TI MEMORIAL HERMANN SURGICAL HOSPITAL FIRST COLONY

**ÀKỌLÉ ÒFIN:** Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó

**DÉÈTÌ ÀTẸ̀JÁDE:** 02/11/2019
**Ẹ̀DÀ:** 3

---

**ÈRÈDÍ ÒFIN:**

Èrèdí Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó yìí ("FAP") ni láti pèsè ìlànà kan fún dídámọ̀ àti pípèsè ìrànlọ́wọ́ owó fún àwọn tí Memorial Hermann Surgical Hospital First Colony (“MHSHFC”) ńṣiṣẹ́ sìn láàrín agbègbè rẹ̀.

MHSHFC jẹ́ alájọṣiṣẹ́ ti Memorial Hermann Health System (MHHS), èyítí ń ṣiṣẹ́ láti mú èrèdí ìyọ̀nda ti MHHS dàgbà. Memorial Hermann Health System (“MHHS”) ńlo Kóòdù Ìpowówọlé Abẹ́lé òfin § 501(c)(3) àwọn ilé-ìwòsàn tí wọ́n ní ìwé èrí ìjọba tí wọ́n ń pèsè àwọn ìní ìtọ́jú ìlera ti Harris, Montgomery, Fort Bend àti àwọn agbègbè tí ó yí wọn ká. MHSHFC jọ̀wọ́ ara rẹ̀ láti pèsè àwọn ànfàní agbègbè ní ọ̀nà ìrànlọ́wọ́ owó fún àwọn ènìyàn tí kò ní ìdójútòfò tàbí tí kò kún ojú ìwọ̀n ìdójútòfò, láìsí ẹlẹ́yàmẹ̀yà, tó nílò àwọn iṣẹ́ tó ṣe pàtàkì fún ìlera tàbí ti pàjáwìrì tí kò sì nííṣe pẹ̀lú agbára aláìsàn láti sanwó.

**ÌWÒYE:**

Ohun èlò FAP yìí wà fún Memorial Hermann Surgical Hospital First Colony, ilé-ìwòsàn tó ní àṣẹ ti ìjọba èyítí ń ṣiṣẹ́ láti mú èrèdí ìyọ̀nda ti MHHS dàgbà.

**GBÓLÓHÙN ÒFIN:**

1. Ìṣedéédé pẹ̀lú àwọn ohun iyì MHSHFC ti ojú àánú àti iṣẹ́ ìríjú, ó jẹ́ òfin MHSHFC láti pèsè Ìrànlọ́wọ́ Owó fún àwọn aláìsàn tí kò ní. Síwájú síi, èrèdí FAP yìí ni láti pèsè àtúpalẹ̀ iṣẹ́ lábẹ́ èyítí a ó fún àwọn aláìsàn ní Ìrànlọ́wọ́ Owó fún ìtọ́jú tó ṣe pàtàkì fún ìlera àti pàjáwìrì èyítí MHSHFC ń pèsè.

2. FAP yìí n dá ìlànà ìwé ìbéèrè àti àmúyẹ pàtó kan mọ̀ lábẹ́ èyítí MHSHFC yóò tan Ìrànlọ́wọ́ Owó de ọ̀dọ̀ àwọn ènìyàn tí kò le sanwó tán fún àwọn iṣẹ́ tí a pèsè.

3. FAP yìí kan gbogbo ìtọ́jú pàtàkì ti ìlera tàbí pàjáwìrì èyítí ilé-ìwòsàn MHSHFC ń pèsè. FAP yìí kò nípa lórí àwọn olùpèsè àwọn iṣẹ́ ìlera tí ó yàtọ̀ sí ilé-iwòsàn kò sì kan àwọn iṣẹ́ dókítà. O le rí àtòkọ àwọn olùpèse tí ń ṣe iṣẹ́ pàjáwìrì tàbí ìtọ́jú pàtakì ti ìlera míràn nínú ohun èlò ilé-ìwòsaǹ èyítí àwọn iṣẹ́ rẹ̀ wà lábẹ́ ara FAP yìí, àti àtòkọ àwọn olùpèsè èyítí àwọn iṣẹ́ rẹ̀ kò sí lábẹ́ ara FAP yìí lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa ní: http://memorialhermannfirstcolony.com/financial-assistance-program/ Àwọn ẹ̀dà

oní-pépà lọ́fẹ̀ẹ́ tún wà nílẹ̀ tí a bá bèrè ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn agbègbè ìforúkọsílẹ̀ ilé-ìwòsàn. Àwọn ẹ̀dà oní-pépà lọ́fẹ̀ẹ́ tún wà nílẹ̀ nípa ìfìwé ránṣẹ́ tàbí pípe (281) 312-4012 tàbí 281-312-4000, Àṣàyàn 5.

4. FAP náà ṣàlàyé àmúyẹ tí a lò nípasẹ̀ MHSHFC láti ṣírò iye ẹ̀dínwó Ìrànlọ́wọ́ Owó, tó bá wà, àwọn ìgbésẹ̀ tí MHSHFC yóò gbé láti polongo FAP yìí láàrín agbègbè tí MHSHFC ńṣiṣẹ́ sìn, ìlànà iṣẹ́ tí MHSHFC ń lò láti pinnu àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti ìlànà ìwé ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. Àwọn ìgbésẹ̀ tí MHSHFC le gbé tí a kò bá sanwó ni a ṣàlàyé nínú òfin ọ̀tọ̀, Òfin Ìdíyelé àti Owó Gbígbà ti MHSHFC. A le gba òfin yìí sílẹ̀ lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù ti MHSHFC ní: [http://memorialhermannfirstcolony.com/financial-assistance-program/](http://memorialhermannfirstcolony.com/financial-assistance-program/), tàbí ẹ̀dà oní-pépà lọ̀fẹ̀ẹ́ wà nílẹ̀ ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn ibi agbègbè ìforúkọsílẹ̀ ilé-ìwòsàn. Àwọn ẹ̀dà pépà lọ́fẹ̀ẹ́ tún wà nílẹ̀ nípa ìfìwé ránṣẹ́ tàbí pípe (281) 312-4012 tàbí 281-312-4000, Àṣàyàn 5.

5. Láti yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó, àwọn aláìsàn gbọ́dọ̀ parí ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó kí wọ́n sì fàá kalẹ̀ pẹ̀lú àwọn ìwé àkọsílẹ̀ tí a bèrè fún. Àwọn ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó yẹ láì kọjá ọjọ́ 240 lẹ́yìn déètì owó àkọsílẹ̀ ìdíyelé àkọ́kọ́ tí a fíránṣẹ́ fún èyítí o ń bèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. A le fún ọ ní àwọn yíyáfì kan bí a ti ṣàlàyé nínú Ìlànà Abala 9. Kò sí nnkan kan nínú FAP yìí ti ó borí àwọn òfin àti ìṣedédé ti ìjọba ìbílẹ̀, ìpínlẹ̀ tàbí àpapọ̀ lọ́wọ́ èyítí a ṣe lónìí tàbí tí a ó ṣe ní ọjọ́ iwájú.

6. Iye owó yòówù tí aláìsàn náà bá san ní àpọ̀jù lẹ́yìn ẹ̀dínwó ìrànlọ́wọ́ owó tí a lò ni a ó dá padà fún gbogbo àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìtọ́jú.

7. Àṣẹ olúborí láti pinnu bóyá MHSHFC ti gbé ìgbésẹ̀ tó dára láti pinnu àmúyẹ FAP wà pẹ̀lú Ibi-iṣẹ́ Ìṣòwò Aláìsàn MHSHFC. FAP yìí ni a ṣe láti ṣe ànfàní fún agbègbè MHSHFC tó ṣe déédé pẹ̀lú àwọn iyì ti ojú àànú àti iṣẹ́ ìríjú rẹ̀. Wíwà nílẹ̀ FAP yií kìíṣe ìfúnni ní Ìrànlọ́wọ́ Owó fún èyíkéyìí aláìsàn kan ní pàtó kò sì ṣẹ̀dá àwọn ẹ̀tọ́ àdéhùn tàbí ojúṣe kankan. FAP yìí ni MHSHFC le mú dójú òṣùwọ̀n ní ọjọ́ iwájú kí Ìgbìmọ̀ Aláṣẹ tàbí aṣojú wọn si fọwọ́síi ní èrò tirẹ̀.

8. Àwọn òfin àti ìlànà tí a sọ wọ̀nyí ni ó gbọ́dọ̀ bá ìṣedédé ti ìlú Texas mu àti Òfin § 501(r) ti Kóòdù Ìpowówọlé Abẹ́lé, àti ìlànà tó jọ ara wọn.

## ÀWỌN KÓKÓ Ọ̀RỌ̀ ÀTI ÌTUMỌ̀:

1. *Ìwé Ìbéèrè:* Túmọ̀ sí ìwé ìbèrè kan fún Ìrànlọ́wọ́ Owó tí aláìsàn kan gbọ́dọ̀ fọwọ́sí.

2. *Àkókò Ìbéèrè:* Ní Àkókò Ìbéèrè, MHSHFC yóò gbà yóò sì ṣiṣẹ́ lórí ìbéèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó. Àkókò Ìbéèrè bẹ̀rẹ̀ ní ọjọ́ tí a pèsè ìtọ́jú fún ẹnìkan ó sì parí ní ọjọ́ 240 lẹ́yìn déètì ìwé ìdíyelé àkọ́kọ́ fún ìtọ́jú náà.

3. Iye Owó Tí A Máa Ń Béèrè *Lápapọ̀ (AGB)*: Àwọn aláìsàn tó yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a kò ní díyelé fún ìtọ́jú pàtàkì ti ìlera àti pàjáwìrì ju iye tí a máa ń bèrè lápapọ̀ (AGB) lọ lọ́wọ́ àwọn aláìsàn tó ní ìdójútòfò.

    a. Ìdá ọgọ́rùún AGB ti MHSHFC ni a ń ṣírò nípa lílo ìlànà "wo-ẹ̀yìn wò", èyí tó jẹ́ àpapọ̀ ti ìsanwó owó-fún-iṣẹ́ Medicare tí a gbà láàyè tí a sì pín nípa àpapọ̀ iye owó fún àwọn tí a bèrè ṣáájú sáà olóṣù 12 náà. Àwọn ẹ̀dínwó tí a pèsè fún àwọn aláìsàn tó yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a ó ṣàtúnyẹ̀wò sí òdíwọ̀n ìdá ọgọ́rùún tí AGB gbà láàyè láti ṣarídájú pé a kò díyelé àwọn aláìsàn ju AGB lọ.

    b. Àwọn ìdá ọgọ́rùún AGB ni a le rí nínú Àfihan A - Ìṣirò Iye Owó Tí A Máa Ń Béèrè Lápapọ̀ ti FAP.

    c. Àtúnyẹ̀wo Ìdá Ọgọ́rùún AGB ni a ó ṣírò ní ọdọdún ni a ó sì ṣàmúlò ní ọjọ́ 120 lẹ́yìn ìbẹ̀rẹ̀ kàlẹ́ndà ọdún.
4. *Àpapọ̀ Owó-àpawọlé Ẹbí Ní Ọdún:* Àròpọ̀ owó Ẹbí kan láàrín ọdún àti ànfàní owó lọ́wọ́ láti orísun gbogbo ṣáájú owó-orí, yàtọ̀ sí àdínkù owó tí a san fún àtìlẹ́yìn ọmọ, tí a le jábọ̀ fún Iṣẹ́ Ìpowówọlé Abẹ́lé United States. Lára owó-àpawọlé ẹbí ni, ṣùgbọ́n kò pín sí, àwọn owó tí a gbà, owó àjẹmọ́nú àìníṣẹ́, owó àjẹmọ́nú òṣìṣẹ́, Owó Ìtọ́jú Ìjọba, Àfikún Owó Ìtọ́jú Ìjọba, ìrànlọ́wọ́ gbogbogbò, àwọn ìsanwó arúgbó, àwọn ànfàní ẹni tó yọ nínú ewu, owó-àpawọlé ìfẹ̀yìntì, owó èlé, owó ìpín, owó lẹ́yìn ìtúká ìgbeyàwó, àtìlẹ́yìn ọmọ, àti àwọn orísun míràn.

5. *Àwọn Iṣẹ́ Àṣàyàn:* Àwọn iṣẹ́ láti yanjú ìṣòro kan tí kò nílò abójútó ojú-ẹsẹ̀. Àwọn iṣẹ́ àṣàyàn kún àwọn ìlanà tó dára fún aláìsàn, ṣùgbọ́n tí kò jẹ́ kánjúkánjú ó sì pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ tó ṣe pàtàkì fún ìlera àti àwọn isẹ́ tó ṣe pàtàkì tí kìíṣe ti ìlera, bii oge àti iṣẹ́ abẹ eyin tí a ṣe láti ṣàmúgbòrò ojú nìkan tàbí àwọn ìlànà míràn tí a yàn èyítí kò sí lábẹ́ àwọn ètò ìdójútòfo ìlera. Àwọn iṣẹ́ àṣàyàn tí kò ṣe pàtakì fún ìlera ni a kò ní wòye fún Ìrànlọ́wọ́ Owó.

6. *Àwọn Iṣẹ́ pàjáwìrì:* Àwọn iṣẹ́ tí a pèsè fún aláìsàn kan fún àìsan kan pẹ̀lú àmì tó lágbára púpọ̀ (pẹ̀lú ìrora tó pọ̀jù), èyítí ó jẹ́ wípé àìsí àbójútó ìlera lójú ẹsẹ̀ ni a rò wípé ó le yọrísí wípé fífi ìlera irú ẹni náà (tàbí èyi tó nííṣe pẹ̀lú olóyún, obìnrin náà tàbí ọmọ rẹ̀ tí a kò tíì bí) sí ewu ńlá, tàbí ṣokùnfà àlébù tó lágbára sí iṣẹ́ ara, tàbí àìle ṣiṣẹ́ mọ́ fún èyíkéyìí ẹ̀yà ara.

7. *Àwọn Ìṣe Owó Gbígbà Ní Ọ̀nà Ọ̀tọ̀ (ECAs):* Èyí ni àwọn ìṣe owó gbígbà tó nílò ìlànà iṣẹ́ òfin àti ti adájọ́, ó sì tún le kan àwọn iṣẹ́ míràn bíi títa gbèsè fún ẹlomíràn tàbí jíjábọ̀ àlàyé tó léwu sí àwọn aṣojú tàbí ilé-iṣẹ́ kírẹ́dìtì. MHSHFC kìí ṣàmúlò ECAs, bẹ́ẹ̀ni kò gba àwọn aṣojú owó gbígbà rẹ̀ láti ṣàmúlò ECAs. Àfikún ìfitónilétí lórí àwọn òfin owó gbígbà MHSHFC ni a le rí nínú Àwọn Òfin Ìdíyelé àti Owó Gbígbà MHSHFC ọ̀tọ̀; ti òfin yìí wà lórí ayélujára lọ́fẹ́ ní: http://memorialhermannfirstcolony.com/financial-assistance-program/ tàbí àwọn ẹ̀dà pépà ọ̀fẹ́ wà nílẹ̀ tí a bá bèrè ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti agbègbè ìforúkọsílẹ̀ ilé-ìwosàn tàbí nípa pípe (281) 312-4012 tabí 281-312-4000, Àṣàyàn 5.

8. *Ẹbí:* Aláìsàn náà, olólùfẹ́ aláìsàn/alábàágbé ti ìjọba, àwọn òbí tàbí alágbàtọ́ aláìsàn (tó bá jẹ́ ọmọdé), àti èyíkéyìí ẹnití a ń bọ́ tí a bèrè lórí ìdápadà owó-orí àpawọlé ti òbí tàbí aláìsàn, tí ó sì ń gbé láàrín mọ̀lẹ́bí alágbàtọ́ tàbí òbí tàbí aláìsàn.

9. Ipele Àìní Ìjọba *Àpapọ̀ ("FPL")*: Ipele owó-àpawọlé tó yẹ ki ẹnìkan wà nínú ipele ìwọ̀n àìní. Ipele owó-àpawọlé yìí yàtọ̀ nípasẹ̀ ìwọ̀n ẹbí náà. A ń ṣàfikún ipele àìní náà ní ọdọọdún nípasẹ̀ Ẹ̀ka Iṣẹ́ Ọmọnìyàn àti Ìlera ti United States tí a sì ntẹ̀ ẹ́ jáde nínú Àkọsílẹ̀ Ìjọba Àpapọ̀. Fún àwọn èrèdí FAP yìí , ipele àìní tí a ṣàfihàn nínú àwọn ìtọ́ni tí a tẹ̀jáde wọ̀nyí ṣojú àpapọ̀ owó-àpawọlé. FPL tí a lò fún àwọn èrèdí FAP yìí ni a ó máa ṣàfikún ní ọdọọdún. FPL ìwòyí ni a le rí nínú Àfihàn B - Àwọn Ìtọ́ni Àìní ti Ìjọba Àpapọ̀.

10. *Ìrànlọ́wọ́ Owó:* Ìrànlọ́wọ́ Owó túmọ̀ sí ìrànlọ́wọ́ tí MHSHFC ń fún àwọn aláìsàn tó yẹ fún àwọn amúyẹ owó kan pàtó àti àwọn ohun àmúyẹ míràn bí a ti túmọ̀ nínú FAP láti ràn wọ́n lọ́wọ́ láti gba àwọn ohun àmúlò owó tó ṣe pàtàkì láti san fún àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera tó ṣe pàtakì tàbí pàjáwìrì èyítí MHSHFC ń pèsè nínú ètò ilé-ìwòsàn kan. Àwọn aláìsàn tó yẹ le kan àwọn aláìsàn tí kò ní ètò ìdójútòfò, àwọn aláìsàn tí owó-àpawọlé wọn kéré, àti àwọn aláìsàn tó ní ààbò díẹ̀ ṣùgbọ́n tí wọn kò le sanwó díẹ̀ tàbí gbogbo àwọn ìdíyelé ìlera wọn tó kù.

11. *Àwọn Iṣẹ́ Ìlera Tó Ṣe Pàtàkì:* Àwọn iṣẹ́ tabí ohun èlò tí a pèsè fún àyẹ̀wò, ìtọ́jú tààrà, àti ìtọ́jú àìsàn kan, ṣe déédé fún gbèdéke iṣẹ́ ìlera tó péye ní àyíká, ni ó wà lábẹ́ tí a sì ríi bí èyítí ó ṣe patàkì fún ìlera nípasẹ̀ àwọn ètò Medicare àti Medicaid, kò sì wà fún ìrọ̀rùn aláìsàn tàbí dókítà nikan. Àwọn iṣẹ́ tó ṣe pàtàkì fún ìlera kò kan iṣẹ́ abẹ fún oge tabí àwọn iṣẹ́ tí kìíṣe ti ìlera, bíi àwọn iṣẹ́ ìkẹ́gbẹ́, ẹ̀kọ́ tàbí iṣẹ́-ọwọ́.

12. *Ìsọníṣókí Èdè Tó Lọ Tààrà ("PLS"):* Lára Ìsọníṣókí èdè tó lọ tààrà ti FAP MHSHFC ni a ti rí: (a) àlàyé díẹ̀ ti àwọn ohun àmúyẹ àti ìrànlọ́wọ́ tí a ń fúnni; (b) àtòkọ ti ojúlé wẹ́ẹ̀bù àti àwọn ibi àfojúrí tí wọ́n wà tí a ti le gba àwọn ìwé ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó; (c) àwọn ìtọ́ni lórí bí a ti le gba ẹ̀dà oní-pépà ọ̀fẹ́ ti FAP; (d) àlàyé nípa kíkàn síni fún ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú ìlànà ìbéèrè; (e) wíwà nílẹ̀ fún ìtúmọ̀ èdè ti FAP àti àwọn ìwé míràn tó jọ ara wọn; àti (f) gbólóhùn ijẹ́rìísi pé àwọn aláìsàn tí a pinnu pé wọ́n yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a kò ní díyelé ju iye owó tí a ń bèrè fún pàjáwìrì tàbí àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera tó ṣe pàtàkì.

13. *Àwọn Ìgbésẹ̀ Tó Ní Ìtumọ̀:* MHSHFC yóo gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó ní ìtumọ̀ láti pèsè àlàyé fún aláìsàn nípa FAP ti MHSHFC nípa fífún àwọn aláìsàn ní Ìsọníṣókí Èdè Tó Lọ Tààrà ti FAP sí aláìsàn ṣáájú kí a tó fi sílẹ̀ ní ilé-ìwosàn. Ní àfikún, MHSHFC yóò gbé àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí láti wí fún àwọn aláìsàn nípa MHSHFC FAP.

    a. *Àwọn Ìbéèrè Tí Kò Péye:* Tí aláìsàn náà àti/tàbí Ẹbí bá fa ìwé ìbéèrè tí kò péye kalẹ̀, MHSHFC yóò pèsè ìfitónilétí tí a fọwọ́kọ tí ń ṣàlàyé irú àfikún àlàyé tàbí ìwé àkọsílẹ̀ tó nílò.

    b. *Àwọn Ìbéèrè Tó Péye:* Tí aláìsàn náà àti/tàbí mọ̀lẹ́bí aláìsàn náà bá fa ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó tó péye kalẹ̀, MHSHFC yóò pèsè ìfitónilétí

àfọwọ́kọ tí ń sọ nípa ìpinnu yálà aláìsàn náà yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ní àkókò tó yẹ yóò sì sọ fún aláìsàn náà ní kíkọ nípa ìpinnu (pẹ̀lú, tó bá yẹ, ìranlọ́wọ́ èyítí aláìsàn náà yẹ fún) àti àwọn ìdí fún ìpinnu yìí. Ìfitónilétí yìí yóò tún pẹ̀lú iye ìdá ọgọ́rùún Ìrànlọ́wọ́ Owó (fun àwọn ìbéèrè tí a fọwọ́sí) tàbí (àwọn) ìdí fún sísẹ́, àti iye owó sísan tí a ń retí lọ́wọ́ aláìsàn náà àti/tàbí Ẹbí tó bá wà. Aláìsàn náà àti/tàbí Ẹbí yóò máa gba àkọsílẹ̀ owó ní àkókò àyẹ̀wò ti ìbéèrè tó parí.

c. *Àwọn Àkọsílẹ̀ Owó Aláìsàn:* MHSHFC yóo fi oríṣìí àkọsílẹ̀ owó ránṣẹ́ tí ń ṣàlàyé àṣùwọ̀n aláìsàn àti iye tó yẹ láti san. Àwọn àkọsílẹ̀ owó aláìsàn yóo pẹ̀lú ìbéèrè kan wípé ó jẹ́ ojúṣe aláìsàn láti wí fún MHSHFC nípa wíwànílẹ̀ èyíkéyìí ààbò iṣẹ́ ìdójútòfò ìlera kan, àkíyèsí MHSHFC FAP, nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ kan láti bèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti àdírẹ́sì ojúlé-wẹ́ẹ̀bù níbi tí a ti le gba àwọn ìwé FAP.

d. *Ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSHFC*: Àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSHFC yóò ṣe àgbéjáde àkíyèsí ní àwọn ibi tí ó ṣe pàtàkì pé Ìrànlọ́wọ́ Owó wà nílẹ̀, pẹ̀lú àlàyé ìlànà iṣẹ́ ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. MHSHFC yóò ṣàgbéjáde FAP yìí pẹ̀lú àtòkọàwọn olùpèsè tó wà lábẹ́ àti àwọn tí kò sí lábẹ́ FAP, ìsọníṣókí èdè tó lọ tààrà, ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti Òfin Gbígbà àti Ìdíyelé lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù ti MHSHFC: http://memorialhermannfirstcolony.com/financial-assistance-program/. MHSHFC yóò ní àwọn ẹ̀dà oní-pépà ọ̀fẹ́ ti àwọn ìwé wọ̀nyí nílẹ̀ tí a bá béèrè ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn ibi ìforúkọsílẹ̀.

14. *Aláìsàn tí Ìdójútòfò rẹ̀ kò péye:* Aláìsàn kan tó ní ààbò díẹ̀ tàbí pátápátá lábẹ́ òfin kan ti ìdójútòfò tó jẹ́ nípa gbígba ìtọ́jú pàtàkì ti ìlera tàbí pàjáwìrì ní àwọn ináwó tó kọjá agbára wọn láti san owó tókù fún ìtọ́jú tí wọn ń gbà.

15. *Aláìsàn tí kò ní ìdójútòfò:* Aláìsàn tí kò ní ààbò díẹ̀ tàbí rárá lábẹ́ òfin ti ìdójútòfò ìlera tí kìí sì íṣe ẹnití ń jẹ ànfàní lábẹ́ ìdójútòfò ìlera àdáni tàbí ti ìjọba, ànfàní ìlera, tàbí ètò ààbò ìlera míràn (pẹ̀lú, láìsí òdiwọ̀n, ìdójútòfò àdáni, Medicare, tàbí Medicaid, tàbí Ìrànlọ́wọ́ Ẹnití A Dá Lọ́ràn) àti tí ọgbẹ́ rẹ̀ ko ní owó àjẹmọ́nú nínú fún àwọn èrèdí owó àjẹmọ́nú àwọn òṣìṣẹ́, ìdójútòfò ọkọ̀, tàbí gbèsè tàbí ìdójútòfò ẹlomíran, bí MHSHFC ti pinnu èyítí ó dá lórí àwọn ìwé àti àlàyé tí a pèsè nípa aláìsàn náà tàbí tí a gbà lati àwọn orísun míràn, fún ìsanwó awọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera èyítí MHSHFC ń pèsè.

## <u>ÀMÚYẸ ÀTÚNYẸ̀WÒ:</u>

1 *Ìbánisọ̀rọ̀:* Láti jẹ́ kí àwọn aláìsàn, ẹbí, àti àpapọ̀ àdúgbò wa mọ̀ nípa wíwà nílẹ̀ Ìrànlọ́wọ́ Owó, MHSHFC yóò gbé oríṣìí ìgbésẹ̀ láti wí fún àwọn aláìsàn àti alèjò sí ilé-ìwòsàn rẹ̀ nípa ti wíwà nílẹ̀ Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti láti ponlogo FAP yìí sí awọn ará àdúgbò èyítí ilé-ìwòsàn kọ̀ọ̀kan ń̀ṣiṣẹ́ sìn. Àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí pẹ̀lú:

a. *Ìyọ́nda Aláìsàn:* Ìyọ̀nda ìtọ́jú ìlera èyítí a buwọ́lù nígbà tí a ń forúkọsílẹ̀ fún àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera pẹ̀lú gbólóhùn kan wípé tí a bá nílò iṣẹ́ àànú, ìpinnu

àmúyẹ ni a gbọ́dọ̀ béèrè fún tí a bá fẹ́ gba ẹni náà wọ ilé-ìwosàn náà tàbí tí a bá ti gba ìwé ìdíyelé ohun tí a kọ tàbí àkọsílẹ̀ owó.

b. *Ìdámọ̀ràn Owó:* A gba àwọn aláìsàn MHSHFC nímọ̀ràn láti wá àlàyé láti ọ̀dọ̀ olùdámọ̀ràn owó ti ilé ìwòsan wọn tí wọ́n bá ń dojúkọ ìṣòro láti sanwó fún gbèsè wọn ní ilé-ìwòsàn. Àwọn olùdámọ̀ràn owó wa yóò sa gbogbo ipá láti ran àwọn aláìsàn tí kò ní ìdójútòfò, tí ìdójútòfò rẹ̀ kò péyé, tàbí tí n dojúkọ àwọn ìpèníjà owó tó níìṣe pẹ̀lú sísan owó àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera tí a npèsè. Àwọn olùdámọ̀ràn owó le tọpinpin àwọn aláìsan fún àmúyẹ fún oríṣìí àwọn ètò owó tí ìjọba gbésílẹ̀, ṣe ìrànwọ́ fún owó àjẹmọ́nú ti àwọn òṣìṣẹ́ tàbí ìbéèrè gbèsè, ṣètò ìgbà ìsanwó tí a fàgùn, tàbí ṣèrànwọ́ fún àwọn aláìsàn láti béèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó.

c. *Ìsọníṣókí Èdè Tó Lọ Tàárà àti Ìbéèrè:* Ẹ̀dà oní-pépà kan ti isọníṣókí èdè tólọ tàárà ti FAP ti MHSHFC àti ẹ̀dà pépà kan ti ìwé ìbèrè Ìranlọ́wọ́ Owó ni yóò wà nílẹ̀ fún gbogbo àwọn aláìsàn ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ àkókò iṣẹ́ àṣehàn wọn. MHSHFC yóò ní àwọn ẹ̀dà oní-pépà ọ̀fẹ́ ti àwọn ìwé àkọsílẹ̀ wọ̀nyí nílẹ̀ tí a bá béèrè ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn ibi ìforúkọsílẹ̀. Àwọn ẹ̀dà ìwé ọ̀fẹ́ oní-pepa tún wà nílẹ̀ nípasẹ̀ ìfìwé ránṣẹ́ tàbí pípe 281-312-4012 tàbí 281-312-4000, Àṣàyàn 5.

d. *Àwọn Ẹ̀dà Tí A Túmọ̀ Wà Nílẹ̀:* MHSHFC ń túmọ̀ FAP, Ìsọnìṣókí Èdè Tó *Lọ* Tàárà, ìwé ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti Òfin Ìdíyelé àti ti Owó gbígbà rẹ̀ fún àwọn tí kò le sọ èdè Gẹ̀ẹ́sì dáradára èyí tí kò tó ìdá márùún nínú ọgọ́rùún (5%) tàbí 1,000 àwọn ènìyàn ti agbègbè èyítí ohun èlò ilé-ìwòsàn náà ńṣiṣẹ́ sìn. MHSHFC yóò jẹ́ kí àwọn ẹ̀dà àkọsílẹ̀ wọ̀nyí wà nílẹ̀ lọ́fẹ̀ẹ́ lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSHFC àti tí a bá bèrè ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn ibi ìforúkọsílẹ̀ ti ilé-ìwosàn. Àwọn ẹ̀dà ìwé ọ̀fẹ́ oní-pepa tún wà nílẹ̀ nípasẹ̀ ìfìwé ránṣẹ́ tàbí pípe 281-312-4012 tàbí 281-312-4000, Àṣàyàn 5.

e. *Àmì Ìpolówó:* Gbogbo àmì Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a ó ṣàfihàn dáradára ní àwọn ibi tó ṣeé rí sí gbogbo ènìyàn, àti pẹ̀lú, ṣùgbọ́n kò parí sí, ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn ibi ìforúkọ́sílẹ̀ aláìsàn. Àmì Ìpolówó náà yóò tọ́ka pé Ìrànlọ́wọ́ Owó wà nílẹ̀ àti nọ́mbà fóònù láti fi bá olùdámọ̀ràn owó sọ̀rọ̀ fún àlàyé síwájú síi.

f. *Ojúlé wẹ́ẹ̀bù*: Àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSHFC yóò ṣe àgbéjáde àkíyèsí ní àwọn ibi tí ó ṣe pàtàkì pé Ìrànlọ́wọ́ Owó wà nílẹ̀, pẹ̀lú àlàyé ìlànà iṣẹ́ ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. MHSHFC yóò ṣàgbéjáde FAP rẹ̀ pẹ̀lú àtòkọ àwọn olùpèsè tó wà lábẹ́ àti àwọn tí kò sí lábẹ́ FAP, ìsọníṣókí èdè tó lọ tàárà, ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti Òfin Owó Gbígbà àti Ìdíyelé lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù ti MHSHFC: [http://memorialhermannfirstcolony.com/financial-assistance-program/](http://memorialhermannfirstcolony.com/financial-assistance-program/)

g. *Àwọn ìdíyelé aláìsàn àti àkọsílẹ̀ owó:* Àwọn àkọsílẹ̀ owó aláìsàn yóo pẹ̀lú ìbéèrè kan wípé ó jẹ́ ojúṣe aláìsàn láti wí fún MHSHFC nípa wíwà nílẹ̀ èyíkéyìí ààbò iṣẹ́ ìdójútòfò ìlera kan, yóò sì kan àkíyèsí MHSHFC FAP, nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ kan láti béèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti àdírẹ́sì ojúlé-wẹ́ẹ̀bù níbití a ti le gba àwọn ìwé Ìrànlọ́wọ́ Owó.

h. Ìfìwé ránṣẹ tàbí fakisi: Àwọn aláìsàn le fi ìbéèrè àfọwọ́kọ ránṣẹ́ tàbí fakisi rẹ̀ fún àwọn ẹ̀dà ọ̀fẹ́ ti àwọn ìwé yìísí àdírẹ́ẹ̀sì ìsàlẹ̀ kó sì ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ orúkọ ẹnìkọ̀ọ̀kan àti àdírẹ́ẹ̀sì dídápadà èyítí wọ́n fẹ́ kí MHSHFC fi ránṣẹ́ sí.

Memorial Hermann Surgical Hospital First Colony
Attn: Financial Assistance
16906 Southwest Freeway
Sugar Land, Texas 77479
FAKISI: 281-566-54717

2. *Ìpinnu Àmúyẹ:* Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a ń pinnu gẹ́gẹ́ bí àwọn ilànà tó kan àyẹ̀wò oníkálùkù nípa bí wọ́n ti nílò owó sí. Àwọn ìlànà náà ni a ṣàlàyé nísàlẹ̀ yìí:

a) Ìlànà ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, nínu èyítí aláìsàn tàbí olùfọwọ́sọ̀yà gbọ́dọ̀ sowọ́pọ̀ kó si fún wa ní àlayé nípa owó tàbí ara rẹ̀ àti àwọn ìwé tó ṣe pàtàkì láti ṣe ìpinnu ti àìní owó;

b) MHSHFC yóò tiraka láti pinnu bóyá ẹnìkan yẹ fún FAP láti kan pípèsè ìfitónilétí fún aláìsàn náà nípa FAP ti MHSHFC nínú Ìṣọníṣókí Èdè TóLọ Tàárà ṣáájú kí a tó fi wọ́n sílẹ̀ ní ilé-ìwòsàn. Ní àfikún, MHSHFC yóò gbé àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí láti wífún àwọn aláìsàn nípa FPA ti MHSHFC.

i) *Àwọn Ìbéèrè Tí Kò Péye:* Tí aláìsàn náà àti/tàbí Ẹbí bá fa ìbéèrè tí kò péye kalẹ̀, MHSHFC yóò pèsè ìfitónilétí tí a fọwọ́kọ tí ń ṣàlàyé irú àfikún àlàyé tàbí ìwé tó nílò láàrín ọjọ́ márùnlélógójì (45) tí a gba ìwé ìbéèrè àkọ́kọ́.

ii) *Àwọn Àkọsílẹ̀ Owó Aláìsàn:* Àwọn àkọsílẹ̀ owó aláìsàn yóo pẹ̀lú gbólóhùn kan wípé ó jẹ́ ojúṣe aláìsàn láti wí fún MHSHFC nípa wíwà nílẹ̀ èyíkéyìí ààbò iṣẹ́ ìdójútòfò ìlera kan, àkíyèsí FAP ti MHSHFC, nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ kan láti béèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti àdírẹ́sì ojúlé-wẹ́ẹ̀bù níbití a ti le gba àwọn ìwé FAP.

iii) *Ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSHFC:* Àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSHFC yóò ṣe àgbéjáde àkíyèsí ní àwọn ibití ó ṣe pàtàkì tí Ìrànlọ́wọ́ Owó wà nílẹ̀, pẹ̀lú àlàyé ìlànà ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. Lórí Ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSHFC: http://memorialhermannfirstcolony.com/financial-assistance-program/ MHSHFC yóò ṣàgbéjáde FAP rẹ̀ pẹ̀lú àtòkọ àwọn olùpèsè tó wà lábẹ́ àti àwọn tí kò sí lábẹ́ FAP, Ìṣọníṣókí Èdè Tó Lọ Tàárà, ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti Òfin Ìdíyelé àti Owó Gbígbà rẹ̀.

iv) *Àwọn Ìwé Tó Wà Nílẹ̀ tí a bá Béèrè:* MHSHFC yóò jẹ́ kí àwọn ẹ̀dà ìwé oní-pepa, ọ̀fẹ́ ti FAP rẹ̀ pẹ̀lú àtòkọ àwọn olùpèsè tó wà lábẹ́ FAP àti tí kò sí lábẹ́ FAP, Ìṣọníṣókí Èdè Tó Lọ Tàárà, ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti Òfin Owó Gbígbà

pẹ̀lú Ìdíyelé wà nílẹ̀ tí a bá béèrè ní ẹ̀ka-iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn agbègbè ìforúkọ sílẹ̀.

c) Ìlò àwọn orísun dátà tó wà nílẹ̀ fún gbogbo ènìyàn lóde èyítí ń pèsè àlàyé lórí agbára aláìsàn tàbí olùfọwọ́sọ̀yà lati sanwó pẹ̀lú iye kírẹ́dìtì nípasẹ̀ TransUnion tàbí Experian;

d) Àtúnyẹ̀wò àwọn àṣùwọ̀n aláìsàn tí a gbà fún àwọn iṣẹ́ ti a ṣe ṣáájú ní MHSHFC àti tàn owó sísan aláìsàn tàbí gbèsè tí kò le san;

e) Àwọn ipele Ìrànlọ́wọ́ Owó tí MHSHFC ti pèsè ni ó dá lórí owó àpawọlé, bí ẹbí ti pọ̀ tó, àti FPL. Àwọn aláìsàn tó ní ìdójútòfò àti àwọn tí kò ní le béèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó; àti

f) Àmúyẹ aláìsàn fún Ìrànlọ́wọ́ Owó yóò dá lórí àwọn ohun àmúyẹ ìsàlẹ̀ yìí ó sì le yàtọ̀ èyí dá lórí ipò owó aláìsàn, àwọn àdínkù owó tó ní ìdí àti wíwà nílẹ̀ ti àwọn ànfààní ètò ìlera alàgàta Àwọn ìtọ́ni àmúyẹ ni a ó máa ṣàtúnyẹ̀wò ní ọdọdún lẹ́yìn tí ìjọba àpapọ̀ bá ti ṣàtẹ̀jáde àwọn ìtọ́ni FPL. Àwọn ẹbí tó ní owó-àpawọlé tó kọjá ìtọ́ni tí a kọ sísàlẹ̀ ni a ó tọpinpin fún àgbéyẹ̀wò ètò ìsanwó.

3. *Àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó Aláìsàn:* Èyí tó dá lórí àwọn FPL, àwọn ohun àmúyẹ wọ̀nyí ni a ó lo láti pinnu àwọn ẹ̀dínwó tí a fifún Àwọn Aláìsàn tí kò ní Ìdójútòfò àti Àwọn tó ní ṣùgbọ́n tí ó nyẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó. Àwọn Aláìsàn Tó Ní Ìdójútòfò tí kò péye gbọ́dọ̀ ní ìdíyéle ìdójútòfò wọn kí wọ́n tó yẹ fún iṣẹ́ àánú. Àwọn ẹ̀dínwó tí a pèsè fún àwọn aláìsàn tó yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a ó ṣàtúnyẹ̀wò sí òdíwọ̀n ìdá ọgọ́rùún AGB láti ṣàrídájú pé a kò díyelé àwọn aláìsàn ju AGB lọ.

   a. **Ìtọ́jú Ọ̀fẹ́**:

      i. Tí Àpapọ̀ Owó-àpawọlé Ẹbí Láàrín Ọdún fún aláìsàn náà bá jẹ́ tàbí kéré sí ìdá ọgọ́rùún nínú igba (200%) ti Àwọn Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀, bí a ti ṣètò rẹ̀ nínú Tábìlì Àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó Àpapọ̀ Owó-àpawọlé (Ẹ̀rí A - Síṣírò Àpapọ̀ Iye Owó Ìdíyelé), aláìsàn náà (tàbí àwọn míràn tó le ní ojúṣe) yóò lẹ́tọ̀ọ́ sí ìtọ́jú ọ̀fẹ́ (ẹ̀dínwó ìdá ọgọ́rún nínú ọgọ́rún) kò sì ní jẹ ìdá kankan nínú ìyókù àṣùwọ̀n lówó.

      ii. Àwọn alaìsàn tó ní ààbò ìlera àkọ́kọ́ nípasẹ̀ Medicare tí wọ́n sì yẹ fún ààbò ìlera kejì nípasẹ̀ Medicaid yóò gba ẹ̀dínwó ìdá ọgọ́rùún nínú ọgọ́rùún (100%) lórí èyíkéyìí owó tó bá kù lẹ́yìn tí a díyelé Medicaid tí a sì gba ìbéèrè tí a yanjú láti THMP tàbí olùsanwó Medicaid Tí a ṣàkóso.

   b. **Ìtọ́jú Ẹ̀dínwó:**

      i. Àwọn Aláìsàn/ẹnìkan tí Àpapọ̀ Owó-àpawọlé Ẹbí Láàrín Ọdún kọjá ìdá igba nínú ọgọ́rùún (200%) ṣùgbọ́n tí kò kọjá ìdá irinwó

nínú ọgọ́rùún (400%) tí Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀ ti ìsinsìnyí le yẹ fún ẹ̀dínwó ti àwọn ìdíyelé sí iye owó tí a máa ń bèrè (AGB) sí àwọn aláìsàn tó ní ìdójútòfò.

ii. Àwọn aláìsàn tó jẹ gbèsè sílẹ̀ lórí ìdíyelé ilé-ìwòsàn le yẹ fún ẹ̀dínwó tí wọ́n bá ní ohun ìmúyẹ wọ̀nyí: 1) ìyókù owó tó ìdá kọjá mẹ́wàá nínú ọgọ́rùún (10%) tí Àpapọ̀ Owó-àpawọlé Ẹbí Láàrín Ọdún tí ẹni náà; 2) wọn kò le san gbogbo owó tàbí díẹ̀ nínú ìyókù ìdíyelé tó kù; àti 3) ìyókù ìdíyelé tó jẹ́ ó kéré jù $5,000. Lábẹ́ àwọn ìṣàkóso wọ̀nyí, aláìsàn tàbí olùfọwọ́sọ̀yà náà gbọ́dọ̀ sowọ́pọ̀ mọ́ ìlanà FAP náà kó si fún wa ní àlayé nípa owó tàbí ara rẹ̀ àti ìwé tó ṣe pàtàkì láti ṣe ìpinnu ti àmúyẹ. Tí a bá fọwọ́síi, aláìsàn náà yóò máa san èyí tí kò ju ìdámẹ́wàá (10%) Àpapọ̀ Owó Àpawọlé Ọdún kan lọ sí gbèsè tó wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ tàbí a ó lo ẹ̀dínwó AGB, èyíkéyìí tó bá kéré tó sì ṣe ànfàní fún ipò ìṣúná-owó ti aláìsàn náà.

4. *Àlàkalẹ̀ Àkókò ti Àmúyẹ:*

a Fún àwọn aláìsàn tí kò ní ìdójútòfò, àwọn ìpinnu Àmúyẹ Tí A Rò àti Ìrànlọ́wọ́ Owo yóò muná dóko látẹyìnwá fún gbogbo àwọn ìyókù owó àdásan àti ìṣẹ̀lẹ̀ ìtọ́jú ìsinsìnyí. A ó pinnu àmúyẹ àwọn aláìsàn èyí tó dá lórí àwọn ohun tí a là kalẹ̀ nínú Abala Ìlànà 3 kò sì ní léwu fún sísanwó kíá àti ní àkókò. Ní àfikún, aláìsàn tó parí Ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a ó fún ní àfikún ìrànlọ́wọ́ owó fún oṣù mẹ́fà láìsí ìgbésẹ̀ kankan mọ́ tí aláìsàn náà nílò. Aláìsàn náà yóò bá MHSHFC sọ nípa èyíkéyìí àyípadà ohun ìní nínú ipò owó aláìsàn náà tó wáyé ní àkókò oṣù mẹ́fà (6) náà èyí tó le kan ìpinnu àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó láàrín ọgbọ̀n ọjọ́ (30) ti àyípadà náà. Ìkùnà aláìsàn kan láti ṣàfihàn ìmúdàgbà ohun ìní nínú owó-àpawọlé Ẹbí le fagi lé èyíkéyìí ìpèsè ti Ìrànlọ́wọ́ Owo nípasẹ̀ MHSHFC lẹ́yìn tí ìmúdàgbà ohun ìní ti wáyé.

5. *Àwọn Iṣẹ́ Pàtàkì ti Ìlera tàbí Pàjáwìrì:* Ìrànlọ́wọ́ owó parí sí àwọn iṣẹ́ pàtàkì ti ìlera àti pàjáwìrì tí a ṣe nínú ilé-ìwòsàn kan. Kò sí ohunkóhun nínú abala yìí ti a ní lọ́kàn láti ṣàyípadà àwọn òjúṣe àti ìlépa àwọn ìṣe MHSHFC sí òfin ìjọba ìpínlẹ̀ tàbí ti àpapọ̀ nípa ìtọ́jú ipò àìsàn pàjáwìrì láìsí agbára fún aláìsàn láti sanwó.

6. *Ìlànà Ìbéèrè*

a. *Bí a ti le Bèrè:* O gbọ́dọ̀ parí ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó kí o sì fàá kalẹ̀, pẹ̀lú àwọn ìwé tí a ó nṣe àtìlẹyìn. Àwọn ẹ̀dà ọ̀fẹ́ ti ìwé ìbéèrè wà nílẹ̀ fún gbígbà sílẹ̀ lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSHFC ní: http://memorialhermannfirstcolony.com/financial-assistance-program/ Àwọn ẹ̀dà oní-pépà lọ́fẹ̀ẹ́ tún wà nílẹ̀ ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn agbègbè ìforúkọsílẹ̀ ilé-ìwòsàn. Àwọn ẹ̀dà oní-pépà lọ́fẹ̀ẹ́ tún wà nílẹ̀

nípasẹ̀ ìfiwé ránṣẹ́ tàbí nípa pípe 281-312-4012 tàbí 281-312-4000, Àṣàyàn 5.

b. Àwọn olùbéèrè le fi ìbéèrè tí a ti kọ ọ̀rọ̀ sí àti àwọn ìwé àtìlẹ́yìn ránṣẹ́ sí olùdámọ̀ràn ètò ìṣúná ti ilé-ìwòsàn tàbí firánṣẹ́ sí àdírẹ́ẹ̀sì tí a kọ sísàlẹ̀ yìí. Àwọn aláìsan le wá olùdámọ̀ràn owó ilé-ìwòsàn kan nípa ṣíṣe àbẹ̀wò sí ibi àlàyé kí o sì béèrè láti bá olùdámọ̀ràn owó sọ̀rọ̀. Fún àwọn ìbéèrè nípa ìlànà ìwé ìbèrè, ìrànlọ́wọ́ láti fọwọ́sí ìwé ìbèrè, tàbí ṣàyẹ̀wò ipò ìwé ìbéèrè tí a fàkalẹ̀, àwọn olùdámọ̀ràn owó ti ilé-ìwosàn wà nílẹ̀ láti ṣèranwọ́ lójúkojú ní ilé-ìwòsàn tàbí o le pe 281-312-4012 tàbí 281-312-4000, Àṣàyàn 5.

c. Ibi tí a le fi àwọn ìwé ìbèrè tó péye ṣọwọ́ sí:

Memorial Hermann Surgical Hospital First Colony
Attn: Financial Assistance
16906 Southwest Freeway
Sugar Land, Texas 77479

-TÀBÍ-

FAKISI: 281-566-5417

d. Àwọn ìbéèrè fún àgbéyẹ̀wò fún Ìrànlọ́wọ́ Owó tàbí Àmúyẹ Tí A Rò ni a le bẹ̀rẹ̀ nípasẹ̀ èyíkéyìí àwọn ènìyàn wọ̀nyí láàrín Ìgbà Ìwé Ìbèrè: (i) aláìsàn tàbí olùfọwọ́sọ̀yà; (ii) aṣojú aláìsàn tàbí olùfọwọ́sọ̀yà; (iii) àṣojú MHSHFC lórúkọ aláìsàn/iwé ìbèrè; tàbí (iv) dókítà tí ń tọ́jú aláìsàn náà.

e. Láìfi ti àwọn àgbéyẹ̀wò tí a kọsílẹ̀ níbò míràn nínú FAP ṣe, ó jẹ́ ojúṣe aláìsàn láti sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àti láti kópa nínú ìlànà ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó. Èyí pẹ̀lú pípèsè àlàyé nípa ààbò ìlera alàgàta míràn tó wà nílẹ̀; tí a ń pèsè ní àkókò àti ní ọ̀nà tó dára gbogbo ìwé àti ìwe ẹ̀rí ti a nílò láti béèrè fún owó nípasẹ̀ ìjọba tàbí àwọn èto míràn (fún àpẹẹrẹ, Medicare, Medicaid, gbèsè alàgàta, Owó Ẹnití a dá lọ̀ràn, abbl.) tàbí láti pinnu àmúyẹ aláìsàn náà fún Ìrànlọ́wọ́ Owó míràn. Ìkùnà láti ṣe bẹ́ẹ̀ le nípa tí kò dára lórí àgbéyẹ̀wò ìbéère Ìrànlọ́wọ́ Owó ti aláìsàn náà. A fẹ́ kí aláìsàn pèsè àlàyé, ìwé ẹ̀rí ati àwọn ìwé láàrín ọgbọ̀n ọjọ́ (30) ti ìbéèrè MHSHFC àyàfi tí a bá fi àwọn àyídà kan tó ṣe dandan tó MHSHFC létí. Ìbèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a gbọ́dọ̀ parí kí aláìsan náà sì buwọ́lùú (tàbí olùfọwọ́sọ̀yà/aṣojú).

f. Olùdámọ̀ràn owó kan le ṣèrànwọ́ fún olùbéèrè ní àkókò ìbéèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó. Tí aláìsàn náà bá ti kú tí a kò sì dá ẹni tó yẹ mọ̀, aṣojú MHSHFC kan le ṣàgbéjáde ìbéèrè kan kí o sì parí ìwé ìbéèrè nípa lílo àlàye àti àwọn ìwé tó wà nílẹ̀.

8. *Owó-àpawọlé Ẹbí:*

Aláìsàn náà le pèsè ọ̀kan nínú ìwé akọsílẹ̀ wọ̀nyí àbí jù bẹ́ẹ̀ lọ láti fìdí owó-àpawọlé Ẹbí múlẹ̀, tí irú àwọn ìwé bẹ́ẹ̀ bá wà nílẹ̀. Tí a bá ní ju ẹnìkan tí ń ṣiṣẹ́ lọ nínú Ẹbí aláìsàn, ẹnikọ̀ọ̀kan gbọ́dọ̀ fa ọ̀kan àbí jù bẹ́ẹ̀ lọ lára àwọn ìwé ìsàlẹ̀ yìí kalẹ̀:

i. Ìwé ìdápadà owó-orí ti owó-àpawọlé ìjọba àpapọ̀ tí fọwọ́sí láìpẹ́;
ii. Àwọn fọ́ọ̀mù W-2 àti 1099 àìpẹ́;
iii. Àjákù ìwé ìsanwó àìpẹ́ (tàbí, tó bá nílò, ẹ̀dà ìwé gbólóhùn àìníṣẹ́, lẹ́tà ìtọ́jú ìjọba, abbl.);
iv. Ìwé gbólóhùn láti ọ̀dọ̀ agbani-ṣiṣẹ́ tí a bá fọwọ́ sanwó; tàbí
v. Èyíkéyìí ìjẹ́rìísímíràn láti ọ̀dọ̀ ẹlòmíràn nípa owó-àpawọlé Ẹbí.

b. Ìwé ìbèrè kan fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a kò níí rí bí àìpéye nítorí ìkùnà láti pèsè ìwé àkọsílẹ̀, tí aláìsàn náà bá ti pèsè ó kéré jù ọ̀kan nínú àwọn ìwé tó ṣàfihàn owó-àpawọlé fún Mọ̀lẹ́bí kọ̀ọ̀kan (pẹ̀lú aláìsàn náà) tí a tòkọ sókè tó sì ti buwọ́lu ìwé ẹ̀rí náà, tàbí tó bá ṣẹlẹ̀ pé aláìsan náà kò le pèsè irú àwọn ìwé náà, tí o ti buwọ́lu ìwé ẹ̀rí.

c. Olùbèrè náà gbọ́dọ̀ buwọ́lu ìwé-ẹ̀rí ti ìwé ìbèrè. MHSHFC le gba ìpinnu rẹ padà tàbí ṣàtúnṣe rẹ̀ tí ẹ̀rí ọjọ́ iwájú bá ṣàfihàn pé olùbèrè náà pèsè àlàyé tó jẹ́ irọ́.

*Àfikún Ìwé Àkọsílẹ̀:* FAP ti MHSHFC kò nílò ìwé àkọsílẹ̀ ohun ìní tàbí ìnáwó. Ṣùgbọ́n Àwọn Olùbèrè le yàn láti pèsè àfikún ìwé àkọsílẹ̀ nípa àwọn ohun ìní, ìnáwó, owó-àpawọlé, àwọn gbèsè tó kù tàbí àwọn àyídà míràn tí yóò ṣàfihàn ìnira owó láti ṣàtìlẹ́yìn fún ìbèrè kan fún Ìrànlọ́wọ́ Owó tó dọ́gba tàbí ju iye owó tí wọ́n lẹ́tọ̀ọ́ sí látàrí FAP yìí.

9. *Àlàyé Irọ́ tàbí Ìṣinilọ́nà:* Tí a bá pinnu pé olubèrè kan ti pèsè àlàyé irọ́ tàbí èyí tó ṣìwá lọ́nà nípa agbára wọn láti sanwó ìtọ́jú ìlera, MHSHFC le sẹ́ àwọn ìbéèrè ti olùbèrè lọ́wọ́lọ́wọ́ tàbí ti ọjọ́ iwájú. Tí a bá pèsè àlàyé irọ́ láìmọ̀, MHSHFC yóo dá ìpinnu rẹ̀ lórí àlàyé tí a túnṣe. Tí a bá ti fún ọ ní Ìrànlọ́wọ́ Owó tẹ́lẹ̀ lórí wípé aláìsàn náà ti pèsè àlàyé irọ́, MHSHFC le mú Ìrànlọ́wọ́ Owo tí a fifún un tẹ́lẹ̀ kúrò, nínú èyí tí MHSHFC ni gbogbo ẹ̀tọ́ tó bá òfin mu láti wá ìsanwó láti ọ̀dọ̀ aláìsàn fún iyekíye tó yẹ fún sísan. Tí ìpèsè àlàyé irọ́ náà bá jẹ́ àṣìṣe, MHSHFC yóò tún ìpinnu rẹ ṣe èyí tí yóò sì dá lórí àlàyé ti a túnṣe.

**<u>ÀWỌN IBI ÌTỌ́KASÍ:</u>**

Òfin Ìfiṣọwọ́ Aláìsàn (EMTALA àti Ìfaramọ́ Òfin Ìfiṣọwọ́ Texas)
Ìsọníṣókí Èdè Tó Lọ Tààrà Ti Ìrànlọ́wọ́ Owó

Ìwé Ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó
Òfin Ìdíyelé àti Owó Gbígbà

**ÀWỌN ẸRÍ:**

Àfihàn A - Ìṣirò Iye Owó Tí A Máa Ń Bèrè

Àfihàn B - Àwọn Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀

*Ó tẹ̀síwájú lójú ewé tókàn.*

## Ẹ̀rí A - Ìṣirò Iye Owó Tí A Máa Ń Bèrè

Iye Owó Tí A Máa Ń Bèrè dá lórí ìṣiṣẹ́ ìdíyelé àti ti kóòdù MHSHFC nlò fún owó Medicare fún iṣẹ́ fún pàjáwìrì tàbí àwọn iṣẹ́ tó ṣe dandan fún ìtọ́jú. Àpapọ̀ ìsanwó tí a gbà láàyè láti Medicare ni a ó pín nípasẹ̀ àpapọ̀ ìdíyelé fún irú ìbéèrè bẹ́ẹ̀, iye náà ni a ó si yọ kúrò nínú 1 láti ṣírò ìdá ọgọ́rùún AGB náà.

**AGB % fún IP (Aláìsàn ilé) = Medicare IP Ìsanwó Tí A Gbà láàyè / Medicare IP Àpapọ̀ Ìdíyelé**
**AGB % fún OP (Aláìsàn òde) = Medicare OP Ìsanwó Tí A Gbà láàyè / Medicare OP Àpapọ̀ Ìdíyelé**

| Ohun Èlò: | Aláìsàn ilé | Aláìsàn òde |
|---|---|---|
| Memorial Hermann Surgical Hospital – First Colony | 30% | 13% |

Ọdún Ìṣúná 2019 (Oṣù keèje 2018 – Oṣù kẹ́fà 2019) Iye Owó AGB nìwọ̀nyìí:

**Iye Owó Tí A Máa Ń Bèrè (AGB): 13%**

**Iye Owó Tí A Máa Ń Bèrè (AGB): 30%**

*Ó tẹ̀síwájú lójú ewé tókàn.*

## **Ẹ̀rí B – Àwọn Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀**

Tábìlì Àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Ètò-ìṣúná Owó Àpawọlé Oṣooṣù Ní Àpapọ̀ ni a ń tún ṣàyẹ̀wò nígbàtí a bá ṣe àwọn àyípadà sí Àwọn Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀. Tábìlì náà ni a ń mú dójú ìwọ̀n lọdọdún.

Tábìlì Àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Ètò-ìṣúná Owó Àpawọlé Oṣooṣù Ní Àpapọ̀ túmọ̀ sí wípé tábìlì owó àpawọlé ìsinsìnyí tí MHSHFC ń lò láti pinnu àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Ètò ìṣúná lábẹ́ FAP yìí.

Tábìlì Àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Ètò-ìṣúná Owó Àpawọlé Oṣooṣù Ní Àpapọ̀ dá lórí Àwọn Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀ àti Tábìlì Àmúyẹ Harris County Hospital District, bí a ti ń ṣàtúnṣe rẹ̀ láti ìgbà dégbà nípasẹ̀ àwọn aṣojú ìjọba tó kàn àti wípé tàbílì tí a ń sọ wà fún àtúnyẹ̀wò.

Jọ̀wọ́ wo tábìlì nísàlẹ̀:

| **Memorial Hermann Surgical Hospital First Colony**<br>Tábìlì Àmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Ètò-ìṣúná Owó Àpawọlé Oṣooṣù Ní Àpapọ̀ | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|
| Àwọn Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀ (FPG) ti 2019<br>Àpapọ̀ owó láàrín ọdún tàbí owó àpawọlé ti oṣooṣù láti yẹ fún ìrànlọ́wọ́ ètò ìṣúná èyí tó dá lórí bí Ẹbí ti pọ̀ sí. | | | | | | |
| | 100% ti FPG | | 200% ti FPG | | 400% FPG | |
| Ìwọ̀n Ẹbí | Owó Àpawọlé Láàrín Ọdún | Owó Àpawọlé Lóṣù | Owó Àpawọlé Láàrín Ọdún | Owó Àpawọlé Lóṣù | Owó Àpawọlé Láàrín Ọdún | Owó Àpawọlé Lóṣù |
| 1 | $12,490 | $1,041 | $24,980 | $2,082 | $49,960 | $4,163 |
| 2 | $16,910 | $1,409 | $33,820 | $2,818 | $67,640 | $5,637 |
| 3 | $21,330 | $1,778 | $42,660 | $3,555 | $85,320 | $7,110 |
| 4 | $25,750 | $2,146 | $51,500 | $4,292 | $103,000 | $8,583 |
| 5 | $30,170 | $2,514 | $60,340 | $5,028 | $120,680 | $10,057 |
| 6 | $34,590 | $2,883 | $69,180 | $5,765 | $138,360 | $11,530 |
| 7 | $39,010 | $3,251 | $78,020 | $6,502 | $156,040 | $13,003 |
| 8 | $43,430 | $3,619 | $86,860 | $7,238 | $173,720 | $14,477 |
| *Fún mọ̀lẹ́bí tó ju ènìyàn 8 lọ, ṣàfikún $4,420 fún ẹni kọ̀ọ̀kan tí a ṣàfikún láti pinnu Ìtọ́ni Àìní Ìjọba Àpapọ̀.* | | | | | | |